# Awon Omo Egbe UPP Sile

(O bere loju ewe kinni)

## Waddell Toro Adura Fun Egba

Alaga na, Ọgbẹni C Wilton-Waddell bẹrẹsi sọrọ, o ni on dupẹ pupọ lọwọ gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ pata pata o ni inu on dun lọpọlọpọ si iru ẹgbẹ bayi nitope ifẹ gidi gidi lo mu ki ẹsẹ awọn ẹgbẹ na pe bayi, iṣiri ni o si jẹ fun on alara paapa, o si tun tọrọ adura pe ki Olu a jẹki ilọsiwuju, iduroṣinṣin, ifẹ ati ododo ki o ma wa titi larin awọn ọmọ ẹgbẹ na ki o si ṣe alabo fun onikaluku wọn.

Lẹhin ti alaga ẹgbẹ na ti sọrọ tirẹ tan, a yan awọn enia kọkan lati origun ti awọn pin ẹgbe na si lati fi ọrọ si awọn ọmọ ẹgbẹ leti gẹgẹbi iriri ati ohun ti o jẹ nkan iṣiri to mu onikaluku wọ ẹgbẹ na.

Oriṣiriṣi ọrọ iwuri, anfani, ifuuni-ni iye ati agbọmalegbagbe ọrọ ti o mu ọgbọn dani ni o ti ẹnu awọn ti awọn dide sọrọ lọjọ na jade.

Lẹhin ọrọ alaga na tun si awọn ọmọ ẹgbẹ leti pẹlu ọrọ iyanju alarinri o ni ki onikaluku wọn ati awọn alaga kekeke mura lati sowọpọ ṣiṣẹ fun idagbasoke ẹgbẹ na ati lati le ma fi suru ati iwa tutu bi omi inu omu ba awọn ọmọ ẹgbẹ wọn lo, ki ifẹ ba le wa, nitoripe ibiti ko ba si ifẹ, ohun gbogbo wa ti enia ba nṣe nibẹ ko ni ni eto ati ilọsiwaju rara.

Ọgbẹni S O Kamson, ti iṣe igbakeji alaga ek nni paapa dide sọrọ, o si ṣ'adura fun ilọsiwaju ninu iṣe ti iṣẹ na ba nṣe.

Gbogbo awọn ti nwọn wa nibi iṣile na ni nwọn fi nkan mimu ati nkan jijẹ te lorun. Diẹ ninu ninu awọn ti a le daruko niyi ninu awọn ọmọ ẹgbẹ na ti o wa nibi iṣile na awọn bi Ọgbẹni P Ọlọmọ, M O Mọmọ J L Aiyedun, L Sosan Jaiyesinmi Ọjẹkunle, H Dindey ati Iya-Afin S Ijale.







*Start comparing machines and you'll find yourself owning a*

**HONDA**

- The machines with automatic clutch, electric starter trafficators and a score of extras.
- The machines with 4-stroke engines. Use petrol ONLY. NO petrol and oil mixture !
- The machines which are built to last

**LEVENTIS MOTORS LTD.**

LAGOS, (E.B.), IBADAN, BENIN, KADUNA, JOS, PORT-HARCOURT & ABA

# Eleti—Ofe D'araba

# Adajo Kan S'ole Onitsha S'ewon L'eko

YABA— Ọdọmọde kan ti orukọ rẹ nje Christopher Mbanefor, eni ọdun mẹta elogun ti awọn ọlọpa ni ṣe ankole onile kiri ni o fi ṣe iṣẹ ṣe ni a gbọ wipe idajọ kan sọ sewọn ọdun marun ni ijẹrin ni Kotu kaba fun ẹsun wipe o fọle, o si ji nkan ko ninu ile Yan ni ọna Ikorodu.

Awọn ọlọpa ni ole arufin na mọ ile onile fọ pupọ, nwọn ni on ko nṣi tirẹ loru, ni ọsan ti nwọn ba ti lọ sibi iṣẹ wọn, ti awọn iyawo wọn ba si ti lọ si ọja ni ọlọṣa yi ma nwọ iyara wọn lọ ti o si ma nko wọn lọru.

Awọn Ọlọpa ni eyiti o ṣe yi bu lọwọ nitoripe gbogbo ẹru ti o ri ji ko ni nwọn gba lọwọ rẹ nigbati o nko wọn lọ.

Ọga ọlọpa ni awọn ko fẹ ki adajọ sanu ọmọ ọlọṣa na nitori wipe o pẹ diẹ ti o ti bẹrẹsi ṣe iṣẹ ọlọṣa ankole kakiri. Nwọn ni lati ilu rẹ Onitsha ni o ti bẹrẹsi kole ki o to wa s'Eko nwọn ni o di igba mefa ti o ti lọ sẹwọn lori ole jija

Adajọ Ọgbẹni Ogunmuyiwa ti o nṣe ẹjọ rẹ bi i lere bi irọ ni nwọn ba pa mọ ọ ọdaran na kiṣe irọ rara ṣugbọn ki adajọ su dari ẹṣẹ na jin on, on ko ni ṣe be mọ. Anajo na ni ti o ba lọ gbẹwa ni ọdun marun ni ọgba ẹwọn a ronu pawada awọn a lu a si simi fuu un rẹ.

di

# Ogedengbe Agbogun-gboro (2)

### Lati Inu Iwe Alufa Atilade

Ija igboro bẹ silẹ ni Ilesha. Ogedengbe ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ do ti Ọdọle ninu ile rẹ. Fun ọjọ mẹta gbako, nwọn ko ri i ṣe ni ohunkohun; ṣugbọn nigbati o bẹrẹ si irẹ awọn enia Ọdọle, on papa lo pa ara rẹ.

Nigbati awọn ara Ilesha gbọ pe Ogunmọla, Bashọrun Ibadan ku, nwọn gba pe akoko yi li a dara julọ lati ta Ibadan laya, Ọtẹ yi da Ogun silẹ larin Ibadan ati Ilesha ni oṣu December, 1867.

Awọn Ijẹsha ti tọju Ilesha silẹ fun ogun yi, nitoripe nwọn mọ pe Ibadan mbọ wa do ti i.

Akere ni Balogun Ibadan ti o ko awọn enia Ibadan lọ si ogun yi, nwọn si ni lati ja ọpọlọpọ ogun ki nwọn to le de Ilesha papa, yika eyiti nwọn ti wa yara nla ati eyi ti awọn ọmọ ogun ki ifẹ ki igba bi Ogedengbe ti mura lati gba silẹ lọnakọna.

Ninu ogun yi ni awọn enia bi Akeredolu, ọmọ Orowusi ẹniti o di olori-ogun Ibadan lẹhin iku ọgagun Akere Latosisa ati Ajayi Ogboriẹfọn, awọn a-r-ogun-yọ fi ara wọn han bi ọkunrin alagbara.

Lẹhin ọpọlọpọ ija, ogun awọn ara Ibadan gba ọna Odo lọwọ awọn Ilesha. Ọna Odo yi ni onjẹ ti nwa fun Ilesha, Nigbati ọna onjẹ yi di agbara ati ma gbeja Ilesa bẹrẹ si dinku.

Ogedengbe ṣe ileri fun Ajayi Ogboriẹfọn pe on ati awọn ọmọ ẹhin o yio fi ilu silẹ, Ajayi Ogboriẹfọn si ṣe ileri pe awọn Ọmọ Ogun Ibadan ko ni fi ọwọ kan wọn.

Gẹgẹbi adehun ni ọjọ kẹrin, oṣu June ni ọdun 1870 Ogedengbe ati awọn janma rẹ fi ilu Ilesha silẹ nwọn si ilẹkun ilu silẹ; awọn ọmọ ogun Ibadan si fi aye silẹ fun wọn lati kọja. Bayi ni awọn ologun Ibadan ṣe ko Ilesha lẹru ninu ogun yi.

( Wo yoku lọju ewe kẹfa )

# Nwon Ri Oku Ogbon Odun Ninu Odo

AMẸRIKA — Nkan kan ninu aye ti a wa yi; n ijẹrin ni awọn ba... awọmi kan sọ ni iwaju adajọ Kotu ilu Amẹrika kan ni awọn ṣe alabapade oku alarede obinrin ti nwọn npe ni Mabel Smith Douglass, ẹni ọdun mẹrindilọgọta, ti o ri si inu omi ... iwọn nkan bi ọgbọn ọdun. Nwọn ni nkankan ko ṣe oku arabinrin na rara.

( Wo yoku loju ewe kẹfa )

# Akowe Banki Kan Lo Sewon Lori Owo Toji

EKO — Adajọ Kotu nla kan ju akọwe ile ifowo pamọ Banki ti uwọn npe ni Barclays Bank ni Ẹhingbẹti 'Eko si ẹwọn ọdun mẹta gbako fun owo awọn oniṣẹ ilẹ na ti o ji gbe laipẹ yi.

George Akakobotu ni orukọ akọwe ọdaran na ajẹ, ẹni ọdun mọkandinlọgọta ni, gẹgẹbi ẹjọ ti awọn ti o wa jẹri fun awọn ọlọpa ro mọ ọ.

Nwọn ni ninu ọdun ti o kọja nigbati awọn alamojuto Ijọba nsọ wipe ki olukuluku lọ parọ owo atijọ ni akọwe ile owo yi ba lọ si inu apoti ifowo pamọ si, o ji ẹgberinla ọdin adọta pọnun (£2,750) bge nibẹ lọ si ile rẹ.

Akọwe ọdaran yi ni nṣe ni gbe owo na lọ si Ṣile kan ni Mushin lati fi parọ owo pepa atijọ, ṣugbọn ni nigbati on de ile ti nwọn ni awọn fẹ parọ owo tuntun nṣe ni awọn oniyawo gba a lọwọ on.

Adajọ ti o ju sẹwọn na ni irọ ni ọdaran yi npa on ko gba ọrọ rẹ gbọ rara

# Eleti—Ofe D'araba

**Plushes, Velvet Velveteen Damask & Building Materials**

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

63, Massey Street, Faji Market,
LAGOS, NIGERIA.

The House Where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed

ELETI–OFE
( A NJU WỌN KOSE WILẸJỌ )

EDITORIAL OFFICE & WORKS
8, Kosọkọ Street, Lagos,
P. O. Box 467

CABLE & TELEGRAM
"ELETI-ỌFẸ" LAGOS
Phone 23370

VOL XIV. NO 889 SATURDAY OCT 5 - OCT 11, 1963

## ORO OLOTU:

# Eja Tuntun wo Inu omi

Gẹgẹbi a ti sọ fun ẹnyin ọkawe wa ninu ọsẹ ti o kọja ninu iwe irohin wipe awọn Yoruba ni ohun aro lati n a fi ki ara wọn fuu orişirişi igba ti o ba ba wọn ati pe ọrọ O DIGBA; O ŞE! ni kiki ti a le fi ki awọn ara ilẹ Nigeria fun iru ominira ti nwọn gbe kalẹ ni ijẹrin o si yẹ ki a tun şi wọn leti fun iru eto Ijọba tun un ti a şẹşẹ gba ti a npe ni Ijọba Alailọba – Ripọbiliki (Republic).

Nitotọ bi ọmọ ba lọkọ, a lẹkọ bi ọmọ ba si to ni ada – iroko baba rẹ a ra ọkan fun un. Ominira ti a bọ şi yi ominira atata ni—ọrọ si pọ nibẹ fun ẹniti o mọ oye.

Ki a mu awada kuro nibẹ a ni awọn ọmọ ti o ni imọ ati oye to lati gbe ẹru ominira tuntun na de ibiti gbogbo ara ilu le fi mọ wipe ominira atata ni a gba nitoto.

Nitotọ ojo ti npa igun wa bọ ọjọ ti pẹ şugbọn gbogbo wa lọmọde lagba ni a nilati jọ dawọ pọ gbe ẹru na sori, ki a si fọwọ wa a mu mọ'ri daradara ki gbogbo rẹ ki o le jọ tu ki o fun olowo ati talaka.

Nisisiyi akoko ti gbogbo wa ti nreti ti de, a ko i forukọ Ọbabinrin Ile Gẹsi şe nkankan mọ gẹgẹbi a ti nşe ni atọdun mọdun wa. Ẹ ja tuntun wọ inu omi, o si yẹ ki iwa wa ati gbogbo şesi wa jẹ ọtun si awọn alabagbe wa.

Awọn ti nwọn ba jẹ alaşẹ Ijọba na, ki nwọn ma fi ibẹru Oluwa şe gbogbo nkan aşẹ ti nwọn ba fẹ gbe jade; ki awọn oşişẹ paapa ma şe işẹ wọn ti aişe imẹlẹ rara, nitoripe a nfẹ ẹkunwo loni, a nfẹ ẹkunwo lọla yi nsu awọn ara ilu ti nwọn nsan owo owo na gẹgẹbi owo-ori orişirişi ti Ijọba ngba lọwọ wọn.

Bi ẹnyin ara ilu ba fẹ mọ bi awọn oşişẹ Ijọba wa ti nşe ọlẹ ati oju kokoro to ẹ lọ sibi ile işẹ wọn bi ile ifiwe ranşẹ (Post Office) tabi ile awọn alaisan (Hospital); awọn ti nwọn wa nibẹ ko fẹ işẹ şe rara a fi ti ẹ ba le fun wọn ni owo ẹhin kun owo oşoşu ti nwọn nsan fun wọn.

Iru bayi kişe IWA OMINIRA bikoşe IWA-INIRA-agbara kan si niyi lati ma fi ni ara wa lara. Awa Eleti-Ọfẹ kişe ọta awọn oşişẹ, agbọran-dun ni a jẹ fun gbogbo ara ilu şugbọn iwa ọlẹ, imẹlẹ ati oju kokoro ti awọn osişẹ Ijọba ilu wa yi nhu. Lẹnu wọn ni ti gbọ wipe a ki şe işẹ ijọba ki a la'gun.

Bẹ a si gbọ ninu Bibeli Mimọ wipe ninu ogun oju wa ri awa yio ti jeun Abọ ọrọ ni a nsọ fun ọmọ-... şugbọn Ọlọrun jẹki ominira tuntun yi ki san wa ... , adura awa onitohun Eleti-Ọfẹ niyẹn.

# Iwe Si Olotu

## Awon Egba Ku Orire

Olotu, ẹ jọwọ ẹ gba mi lati ki gbogbo awọn ọmọ Ẹgba nile ati lẹhin o i fun ọmọ ọba Gbadebọ ti nwọn yan fun ọba Alake tuntun laipẹ yi ti ija ko si, ti ọtẹ ko si.

Awọn agbalagba Ẹgba ti nwọn wa laiye atijọ nigbati Ọba Gbadebọ njọba ni aiye atijọ fi ye wa wipe ilu Abẹokuta kun fun enia nigba tirẹ. Ọpọlọpọ ni nwọn si nsowo, ti nwọn njere.

Gẹgẹ bi aiye ti nlọ yi enia lati ni suru ti o ba fẹ ko enia jọ; adura wa si ni wipe ki o fun Ọba Alake tuntun na ni suru nitoripe awa Ẹgba sọrọ sin.

Kabiyesi Ọba Alake, Gbadebọ Keji ! Ade a pẹ lori, bata a si pẹ lẹsẹ.

Olotu, mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi lati ki ọba wa tuntun na.

Emi ni,

Agọ Owu, Abeokuta
Lalekan Ọmọ Abati

## Owo Repubiliki Ti Wa Nko

Nigbagbogbo ni awọn oşişẹ Ijọba ati awọn oşişẹ ile onişowo ma nbere owo gọbọyi lọwọ awọn ọga wọn ti nwọn iba fẹ gbe eto tuntun kan jade. Ninu ọdun kẹta lọhun nwọn bere owo ominira, nọwn ya wọn lowo kan ti nwọn pe ni Tafawa Balewa.

Ti ọtẹ yi iti nwọn mbere ti o dogun ti o dode mo ro wipe owo-Azikwe ni nwọn a fẹ pe owo na.

Mo si gbọ wipe ki awọn oşişẹ to da işẹ silẹ oguulọgọ wọn ni nwọn ti gba owo oşu kan ti nwọn ya wọn o dara bẹ.

Tani yio san owo repọbiliki fun awọn ti nwọn ko nşişẹ Ijọba bi iru temi bayi? Mo fẹ awọn alamojuto Ijọba paapa mọ wipe inu ọja kanna ni gbogbo wa ti nra ọja

Emi ni,

Mọkọla, Ibadan
T B Alabi

Akiyesi

A nfe asoju fun iwe irohin Eleti-Ofe kakiri ilu okere, e kowe bere lodo Olotu Eleti-Ofe 28, KOSOKO ST LAGOS

# Aseye Igbade Oba Gbadebo Keji Pabambari

ABẸOKUTA—Ki a ko tẹgan kuro nibẹ aṣeyẹ ọjọ ti nwọn ngbe ade le Alaiyeluwa Ọba Adeṣhina Gbadebọ Keji Ọba Alake tuntun lori ni Ake ni Abẹokuta lọjọ Abamẹta (ijẹjọ) ọjọ na pabambari. Ti ẹlẹgan ni o ku, gbogbo ẹsẹ awọn enia patakipataki, awọn lọya, awọn adajọ, awọn ijoye lati ilẹ Yoruba ni nwọn pesẹ sibẹ bamubamu ti gbogbo igun mẹrẹrin ilu Ẹgba kun ṣọṣọ.

Ni ọjọ ti nwọn gbe ade le Ọba Alake tuntun na lori ni o di ẹni ọdun marunleladọta, ibọn marunledọta ni awọn ọdẹ ilu Abẹokuta yin lati ki Ọba na ku orire ti ọjọbi rẹ ti owurọ ọjọ na.

Lẹhin eyi ni gbogbo enia wa bẹrẹsi rọ wọ Afin Ake lati wo iran bawo ni nwọn yio ṣe gbade fun Ọba Alake tuntun nitoripe ọpọlọpọ awọn ọmọ Ẹgba ni nwọn wa ti nwọn ko ni anfani lati ri bi nwọn ti ṣe gbade fun ologbe Ọba Ladapọ Ademọla Keji ninu ọdun 1920-ọdun mẹtalelogoji nisisiyi.

Gbara ti nwọn ti gbade le Ọba na lori ni Gomina Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun, Ọlọla Ọdẹleyẹ Fadahunsi ti bọ siwaju rẹ ti o si gbe iwe aṣẹ rẹ fuu un, gbọgbo ọrunlọgọ awọn enia pejọ ni ẹyẹ igbade ọjọ na si damoso wipe "KABIYESI, ỌBA ALAKẸ, KI ADE KO PẸ LORI KI BATA PẸ LẸSẸ".

Lẹhin eyi ni oriṣiriṣi ọmọ ẹgbẹ saraki saraki ọmọ Ẹgba ti nwọn wa nile ati lẹhin odi wa bẹrẹsi fun Ọba na ni ẹbun oriṣiriṣi; awọn miran fun un ni ni aga ijoko olowoyebiye, awọn miran na a lọrẹ ade-ilẹkẹ ati bata ti o ba ade na ọu.

Olotu Ijọpa Ipinle Iwọ Orun, Oloye S.L. Akinltọa wa dide o sọrọ, o ni on ba awọn ijoye afọbajẹ ilu Ẹrba yọ fun ọna ti nwọn gba fi yan Ọba Alake tuntun na laisi ikunsinu kan larin ilu.

Oloye Akintọla ni on ri wipe ọna ti awọn Ẹgba le fi gqe iyi ati ogo ilu wọn ga ni wipe ki nwọn gbaruku ti Ọba Alake tuntun na ki nwọn fi iwa ọtẹ ati tẹmbẹlẹkun silẹ ki aya nwọn ara ilu le balẹ ki olukuluku ọmọ Ẹgba le sowo ki nwọn jere nile loko.

Pẹlu ẹru ni Ọba Alake tuntun paapa fi bẹrẹsi sọrọ ti o ni ou dupẹ lọwọ gbogbo awọn ọmọ Ẹgba ati awọn Ijoye ilu Ẹgba lọkanrin ati lọọnrin paapa awọn alamojuto Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun fun wahala ti olukuluku wọn ṣe lori ọsọ on.

Ọba Gbadebọ Keji yi ni nkankan pataki ti on fẹ lọwọ awọn Ẹgba ni adura wọn lọsan ati loru ki on le gbe ẹru ilu Ẹgba dori pẹlu awọn Ọba Ẹgba yoku bi Ọba Olowu, Ọba Agura, Ọba Ọshinlẹ ati Olubara, ki ogun ati ọtẹ ki o ma si nigba ti on, ki o rọ tẹru tọmọ lọrun.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

## ONJE ORE AWO

Boya ẹ le gbagbe aworan yi! Aworan ti Olotu Ijọba Apapọṣe, Ọlọla Tafawa Balewa ti nwọn gba ni Ibadan niyi nigbati Olotu na lọ bẹ Ipinlẹ Iwọ Orun wo ti nwọn fun un ni ọgẹdẹ gẹgẹ bi nkan ipanu Oloye Akintọla, Olotu Ipinlẹ na ni o wa pẹlu rẹ ati Ọgbẹni T. O. S. Benson, Dọkita Ọnabamiro ati Ọgbẹni Ọlanrewaju, minisita eto iṣẹ awọn Ọlọpa ti o tẹle Ọlọla Tafawa Balewa lẹhin kakiri irin ajo na nibiti gbogbo wọn njẹ ọgẹdẹ didun.



CARSON PAINTS
AND VANISHES




SOLE AGENTS:
IKORODU TRADING COMPANY
20 & 28, Balogun Street, Lagos.

# Ogedengbe Agbo-gungboro

(O bẹrẹ lọj. ewe kẹta)

Lẹhin ogun yi, Ogedenbe nlọ do si Ita Ogbolu: Nihin ni Ogedengbe ati awọn ọmọ ẹhin rẹ wa, nigbati gbogbo awọn Ijẹsha ati gbogbo ilẹ Ekiti fi d te si ẹgbẹ nla ti a npe ni Ekitiparapọ lati gba ara wọn silẹ lọwọ Ibadan (Ọyọ). Ẹgbẹ ogun tuntun yi rauṣẹ si Ogedengbe lati bẹẹ pe ki o wa ṣe ọgagun fun Ekitiparapọ.

Ogedengbe ko fẹ gba ipe yi nitoripe ko fẹ ba ileri ti o ti ṣe fun awọn ologun Ibadan jẹ pe on ko ni doju kọ wọn ni ogun jija ma. Ṣugbọn nigbati ẹbẹ ati rirọ pọju, Ogedengbe gba lati ṣe Olori ogun Ekitiparapọ.

Bayi ni Ogun Kiriji bẹrẹ eyiti nwọn ja fun ọpọlọpọ ọdun titi Adeyẹmi Alefin Ọyọ bẹ Gomina ti Ijọba Gẹsi ti o wa ni Eko pe ki o ba on pari ija na

Ni ọjọ 23, oṣu September 1886 ni a ṣe ipade ilaja larin awọn Ọọọ ati Ekitparapọ ni agbegbe Imẹsi. Ogedengbe, Seriki ti awọn Ijẹsha jẹ ọkan ninu awọn ẹniti o tọwọ bọ iwe adehun alafia na.

## E Ka

**Oro Akowe Banki ti o lo sewon loju ewe keta**

# Won Ri Oku Ogbon Odun Ninu Odo

(O bẹrẹ loju ewe kẹ a)

Awọn ti o sọrọ ni iwaju adajọ ti o nwa idi kinni fa sababi iku obinrin na ni ninu oṣu September ninu ọdun 1933 ni arabinrin na gbe ọkọ oju omi kan ti o nwa fi gba atẹgun lọ lori adagun omi ti nwọn npe ni Lake Placid ọkọ rẹ na si ri pẹlu rẹ.

Awọn ibatan rẹ wa oku rẹ titi nwọn ko ri i nibẹna, sugbọn ni ẹnu ọjọ mẹta yi ni awọn womi-womi lọ ṣe iṣẹ kan ninu adagun omi na a nigbati nwọn de ibẹ oku okunrin na ni nwọn ri ni isalẹ lọhun.

Nwọn ni egbogi ala kan ti o wa ni Isalẹ omi na ko jẹki oku na bajẹ rara. Ese bata marundinlogoiun ni ibiti nwọn gbe ti gboku arabinrin na jin to ninu odo na,

Awọn ọlọpa ni nkan ti o dun awọn ninu ọrọ oku arabinrin na ni wipe ko ni ẹbi kan laiye mọ ti nwọn ko ba gboku rẹ na fu.

YOUR SPECIALIST FOR ALL
BUILDING MATERIALS
BROSSETTE
(NIGERIA) LTD.
WHARF ROAD - APAPA - (NIGERIA)
P.M.B 1135 - APAPA
At your service
• STOCK
• SPECIAL ORDERS
• TECHNICAL INFORMATIONS

### Students Hold Parties

# Republic Day Celebrations In Britain

LONDON—Nigeria's Republic Day celebrations in London were ushered in by a ball givon by the Nigerian High Commissioner, Alhaji Abdul Maliki, for members of the High Commission staff and Nigerian students in London.

The High Commission also held a reseption last night for British friends of Nigeria at one of London's leading hotels and the Nigerian student association has planned an all-night dance for this weekend.

Students throughout Britain held perties both small and large but perhaps the most impressive was in Cardiff, where the occes on was marked by a flag hoisting ceremony outside the Town Hall by the Deputy Lord Mayor of Cardiff, Alderman F. G. Davis.

"Occasions like this,", said Mr. Isa Suie, Secretary of the Cardiff Branch of the Union of Nigerian Students, who comes from Auchi, "will help strengthen the already close links we have with Britain.

"Nigerian students can always look to the people of Wales for friendship and warm hospitality", he added.

Yesterday evening the students hold a celebration party at the British Council Centre in Cardiff at which Irene, Countries of Plymouth, was chairman. An address of welcome in Hausa was given by Mr. B. A. D. Mallam Gora, who recently arrived in Britain to study sociology and who comes from Zaria.

## British Lawyer For North

LONDON-A distinguished British lawyer, who has been Attorney General in Nyasaland, has been appointed a Legal Draftsman to the Government of Northern Nigeria.

He is Mr Ralph King, who will be sailing to Lagos this month to serve in Nigeria under the Britain-Niger a technical assistance arrangement.

As Attorney General in Nyasaland one of his responsibilities was to supervise the drafting of all Government legislation.

Mr King served in Somaliland as Legal Officer and Crown Council from 1947-1953 when he transferred to Nyasaland- There he was promoted to Attorey General in 1957. He returned to Britain in 1961.

Mr King will bring his wife and younger son to Nigeria. His eldest son and his daughter will remain at school in Britain.

# Britain Buy More Produce From Nigeria

LONDON—Britain's purchases from Nigeria are running at a level £1 1/2 million above those of last year, eccording to figures just published in London by the Board of Trade.

In the first eight months of 1962, Britain bought produce from Nigeria worth £52,250,941. The comparable figure has risen this year to £53,590,143.

The two biggest rises are in petroleum and oilseeds but over the first eight months of thi year, other commodities showing increases are hides and skins, timber, cotton, and products under the heading "coffee, cacoa, tea and spices."

# Nigerian Journalists In Britain For Special Course

LONDON — Two Nigerian journalists have arrived in Britain to join the first course organised by the Thompson Foundation to help trainee newspapermen from developing countries.

The three-months course starting this week in Cardiff, will include practical experience on two of the City's newspapers, The Thomson Foudation was set up recently by Mr, Roy Thomson with a £5 million Trust to train journalists and broadcasters from developing countries.

The Nigerians, Mr Isaac Pepple, a free-lance journalist and feature writer and Mr Folorin Moronkefti Adeeke, Assistant Production Editor with the DAILY EXPRSS, will spend the first week getting to know Cardiff and meeting leading people

They will meet the chairman of the Glamorgan Council, the Mayor of Swansea and the Lord Mayor of Cardiff, There will also be dinner and reception in their honour as Cardiff Castle.

## Scottish-Born British Red Cross Commandant



Miss Moira Dunn, formerly Commandant of a City of Glasgow British Red Cross Society detachment, has been appointed Headquarters Field Officer to Uganda.

# Inu Iya Oba Alake Tun-tun Dun

AKE, ABEOKUTA— Ọlọrun jẹki iṣẹ wa ki o soju wa — adura awọn agbalagba ilẹ Yoruba ni iṣẹ ọkan ninu awọn (iyawo) Ọba Gbadebọ Okunkẹnu Kini ti o gori itẹ ni ilu Abeokuta ninu ọdun 1898, o di ọdun marunlelọgọta n aisiyi, ṣe oju rẹ ni owurọ ijẹjọ nigbati nwọn ngbe ade-ọba ka ọmọ rẹ ti nwọn sọ ni Adeṣina lijọsilori oruko Olori (iyawo Ọba Gbadebọ tijọsi) na ni ỌMỌLỌLA, on ni o bi Ọba Alake tuntun ti o sẹṣẹ gori itẹ yi.

Ni ọjọ gangan ti o di ọdun marunleladọta ti o bi ọmọ rẹ na ni nwọn gbe ade-ọba le lori; ṣe ẹnyin na wa ri wipe ti Olori iya Ọba tuntun na tayọ nitotọ.

Akọwe onirohin Eleti - Ọfẹ ti o lọ sibi ajọyọ igbade Ọba na sọ fun wa wipe nigbati on de ọdọ iya Ọba na nṣe ni o mbu ẹrin si ẹrẹkẹ pẹlu awọn ọrẹ rẹ ti nwọn rọgba yika nibiti nwọn gbe joko si ti nwọn njo gbẹdu ilu Ọba

Boya ẹ le fẹ gbọ ọkan ninu awọn orin aladun ti awọn Ẹgba nkọ lọjọ ti Ọba Alaiyeluwa Gbadebọ Keji gbade na? Ọkan niyi:

O gbe'gba Oyin,
O gbe'gba Oyin,
Igba Oyin lo gbe,
Deṣina Gbadebọ
O gbe'gba Oyin.

Adura wa ni wipe igba oyin ti a gbọ wipe ọba tuntun na gbe ki o doyin ki o ki ilu Ẹgba san tọmọ tagba, ki nwọn ri ere ko ko wa sile. Kabiyesi!

## Alake Tuntun Di Minista Ni Ibadan

IBADAN—Gomina Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ti yan Alaiyluwa Ọba Adeshina Gbadebọ Keji, Alake Ẹgba ti nwọn ṣẹṣẹ gbade fun ri ijẹjọ, si ajọ awọn minista mẹwa ti nwọn yan kun awọn mọkanlelogun ti o ti wa nilẹ.

Ni ijẹta ni Ọba tuntun na sare lọ si Ibadan lati lọ ṣe ibura niwaju Gomina ti o yan na. Orukọ awọn Ọba ti nwọn tun yan ni minista pẹlu rẹ ni Ataọjo ni Oshogbo, Ẹlẹkọle ni Ikọle pẹlu Mọjidi Agbaje ọmọ ologbe Oloye Salami Agbaje ni ọja Ayẹyẹ ni Ibadan

# Eleti—Ofe D'araba

# Awon Oloye Eko Fese Fe e

(o bẹrẹ loju ewe kinni)

Gẹgẹbi ofin eto igbimọ kansulu na, ti nwọn ba ti de awujọ wọn, akọwe agba ijọba ibilẹ na ni o ni lati kọ kawe gbogbo nkan eto ti nwọn ba ti ṣe ninu ipade ti nwọn ṣe gbẹhin fun wọn. Ọgbẹni Sylvester Mayaki tiṣe akọwe-agba ijọba ibilẹ na nisisiyi ka iwe yi fun wọn lana.

Alhaji A. F. Masha tiṣe alaga awọn Kanselọ na wa dide o bẹrẹsi sọrọ, o mu ẹnu kan ọrọ 'abuku' kan ti nwọn ni Ọgbẹni Adeniran Ogunsanya, ọkan ninu awọn kansilọ ọmọ ẹgbẹ Alakukọ sọ ninu ile igbimọ aṣofin wipe awọn gbe iṣẹ alagbaṣe agbepoo le ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ AFẸNIFẸRE (AG) lọwọ Alhaji Masha ni irọ ni nwọn npa mọ awọn, awọn ko gba iṣẹ agbepoo lọwọ ẹnikan rara.

A gbọ wipe kete ti Alaga ti sọ ọrọ yi tan ni kansilọ Alhaji H.P Adebola ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ti bọ siwaju rẹ ti o bẹrẹsi lọgun wipe nkan ti o ba gba ni awọn yio fun un nitoripe ti nwọn ko ba jẹki awọn sọ si ọrọ alaga na "ẸNIKAN KO NI ṢE IPADE NIBI LONI" Akọwe na ṣe alaye o ni eto ofin igbimọ na'ko ni ki ẹnikan sọ si ọrọ alaga.

Ki a to ṣẹju kansilọ Gregory Opkara ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ti fo siwaju tabili akọwe agba Ọgbẹni Mayaki, o ko gbogbo iwe ti nwọn fẹ fi ṣiṣẹ, o da wọn so'de. Ọrọ na wa di bi o ko lọ ki o yago lọna, awọn ọlọpa sare wọle lati dẹrọ ija na fun wọn, awọn kansilọ na ni ki nwọn fi ti wọn ṣe ti wọn.

Gbogbo bi nwọn ti nṣe ijangbọn yi nṣe ni kansilọ Ogunsanya ti o dọrọ na silẹ joko ti o nrẹrin ni tirẹ bi ẹni wipe ko mọ nkan ti o nlọ.

# Iya Pade Agbako

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

ati awọn iya ikoko pẹlu awọn alaisan ti o wa sile iwosan (General Hospital) ni nwọn le pada sile wọn wipe ko si egbogi kankan ti awọn dọkita yio lo fun wọn nibi ipamọ ile iṣẹ wọn dọkita na.

A gbọ wipe ọrọ ko si ogun fun alaisan nwọn yi ko nṣe ọrọ ilu Ilọrin nikan, nwọn ni o fẹrẹ dabi ẹni wipe gbogbo ilu oke ni nwọn ko ri egbogi lo fun awọn alaisan mọ.

Awọn enia kan ni boya awọn oṣiṣẹ ile iwosan awọn alaisan na ti nwọn nji ko lọ sile ati awọn nọọsi ti wọn nse nko lọ sile wọn lati lọ lo fun awọn alaisan na ti nwọn ngba owo lọwọ wọn ni o fa sababi, oju Ọlọrun ni o to o, ṣugbọn a fi Allah bẹ awọn minisita alamojuto eto ilera ilẹ Nigeria ki nwọn jọwọ ba wa ṣe iwadi ọrọ na l'EKO, ni Ibadan, ni Enugu ati ni Kaduna.

P. ed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Phone 23370 Lagos; Editor: (Olotu) Ọla. Ọnatade, 15, Kosoko Street, Box 467, Lagos.